“Dájúdájú èèyàn ti Ọlọhun koriira jù ni alátakò ti o le julọ”

Láti ọdọ Aishah- ki Ọlọhun yọnu si i- lati ọdọ Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- o sọ pé: “Dájúdájú èèyàn ti Ọlọhun koriira jù ni alátakò ti o le julọ”.
[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ pé Ọlọhun ti ọla Rẹ ga n koriira ninu awọn èèyàn ẹni ti o le ni àtakò ti o si maa n sáábà ṣe àtakò, ẹni tí kii tẹ́rí ba fun òdodo, ti o maa n gbìyànjú láti da a pada pẹlu iyàn jíjà rẹ, tabi ki o maa ṣe àtakò lori ododo, ṣùgbọ́n o maa ki aṣeju bọ́ ọ́, o tun maa ṣe àtakò láìní imọ.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/5474